# AYỌ̀ ONIGBAGBỌ́

## Filippi 3:1-3, 7-16, 20, 21; 4:1-13

## ẸKỌ 406 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo: mo si tún wi, Ẹ mã yọ̀" (Filippi 4:4).**

### Onigbagbọ́ ti o Layọ̀

Paulu Apọsteli jẹ Onigbagbọ́ ti o layọ nitori o ti ni iyipada ọkàn. Ọlọrun ti fi awọn iṣipaya iyanu kan hàn an ti o mú inu rẹ̀ dùn, ṣugbọn O si tun kilọ fun Paulu pe yoo jiya fun Ihinrere. O si jiya nitootọ. A ti na Paulu; ọkọ̀ ti rì i, awọn èké arakunrin ti fi i hàn; ebi ti pa a, otutu si ti mú u, a si ti fi i sinu tubu nitori Ihinrere. Sibẹ o le wi pe, "Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa." Laisi aniani, awọn ara Filippi ti o n kọwe si ni akoko yii yoo ranti bi oun ati Sila ti n kọrin nigba ti wọn wà ninu tubu, pẹlu ẹyin wọn ti n tú ẹ̀jẹ jade, ni ibẹwo wọn akọkọ si Filippi. Paulu ko wi pe ki ẹnikẹni ki o ṣe ohun ti oun tikara rẹ̀ kò ṣe. Nipa iriri o mọ̀ pe Ọlọrun yoo ran oun lọwọ ni gbogbo akoko iṣoro ayé, ati pe yoo si fun oun ni ère fun ijolootọ oun.

Ilepa Paulu ti o ga julọ ni lati lọ si Ọrun lati lọ wà pẹlu Jesu. O ni oun ti jiya awọn n kan wọnni nitori ireti ajinde. O mọ̀ pe bi ẹnikan ba pa oun, oun yoo lọ si Ọrun lẹsẹkẹsẹ. O ti ri i nigba ti a n sọ Stefanu ni okuta, o si ti ri ogo ti o farahan ni oju rẹ̀ bi ẹmi rẹ̀ ti n rekọja lọ. O gbọ́ nigba ti Stefanu n wi pe, "Wò o, mo ri ọrun ṣi silẹ, ati Ọmọ-enia nduro li ọwọ́ ọtún Ọlọrun" (Iṣe Awọn Apọsteli 7:56). O n wu Paulu pẹlu lọpọlọpọ lati ri ohun kan naa, o si ṣetan lati fi ohunkohun ti yoo gbà a silẹ ki o ba le ri i. Ero lati ri Jesu paapaa a maa mú inu rẹ̀ dùn pupọ. Nitori eyi ni o ṣe layọ̀ nigbagbogbo. Kò si ẹni ti o le gba ireti yii kuro ninu ọkàn rẹ̀.

Bi a ba ti tun wa bi a di ọmọ Ọlọrun, ati ajogun Rẹ̀. Awa jẹ ajumọjogun gbogbo ogo Ọrun pẹlu Kristi. Jesu ti lọ pèse àye kan silẹ fun wa, ibi ti o logo ju eyi ti a le fi ọkàn rò lọ. Paulu sọ pe bi a ba jiya nihin yii pẹlu Kristi a o ṣe wa logo pẹlu Rẹ̀.

### Ikilọ

Paulu ṣọra lọpọlọpọ lati lo igbesi-ayé rẹ̀ ni ọ̀na ti yoo fi mu un yẹ lati le gbadun Ọrun pẹlu Jesu, o si kilọ fun awọn ara Filippi lati gbé igbesi-ayé wọn ni ọ̀na ti awọn pẹlu yoo fi le gbadun iye ainipẹkun. O kilọ fun wọn lati ṣọra lọdọ awọn ajá, -- orukọ ti o pè awọn eniyan buburu – ati awọn onişẹ buburu, ati awọn onilà. Awọn "onilà" ni awọn Ju ẹlẹsìn ti wọn kò tẹle Jesu ti wọn si n gbiyanju lati dá awọn Onigbagbọ́ lẹkun lati maa tẹle Jesu. Wọn n waasu pe awọn eniyan nilati pa ilana ati eto Ofin mọ́ ki wọn to le ri igbala.

Awọn Ju n tẹnumọ ọ pe iran Abrahamu ni awọn i ṣe, ati pe awọn nikan ni o le lọ si Ọrun. Nigba ti Paulu wi pe, "Awa ni onilà,' ohun ti o n sọ ni pe awa ti a ti tunbi ti a si gbọran si aṣẹ Ọlọrun, ni iṣe ọmọ Abrahamu tootọ. Abrahamu gba Jesu gbọ̀ igbagbọ rẹ̀ si gbà a là, bakan naa ni pẹlu awa ti a tọ Jesu wá pẹlu ironupiwada ti a si gbagbọ́ pẹlu pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun ti O kú fun wa, ni a jẹ́ ọmọ Abrahamu tootọ. "Bi ẹnyin ba si jẹ ti Kristi, njẹ ẹnyin ni irú-ọmọ Abrahamu, ati arole gẹgẹ bi ileri" (Galatia 3:29).

### Igbala ki iṣe nipa Iṣẹ

Nigba ti o ni, "Awa kò si ni igbẹkẹle ninu ẹran-ara," itumọ ohun ti o n sọ ni pe bi awọn obi oun tilẹ jẹ Ju, ti oun si ti fi gbogbo iṣọra pa gbogbo ilana ati eto Ofin mọ́, eyi yii kò lè gbé oun dé Ọrun. Paulu wi pe oun ni ẹtọ gẹgẹ bi ẹnikẹni ti ṣe le ni ẹtọ si inu ẹbi Ọlọrun nipa bibi ti a bi oun sinu idile Ju ati nitori itara ti oun ni fun ẹsin awọn Ju, ṣugbọn oun mọ̀ daju pe iwọnyi kò le ṣe oun yẹ fun Ọrun. O ni: "Ṣugbọn ohunkohun ti o ti jasi ère fun mi, awọn ni mo ti kà si òfo nitori Kristi … mo si kà wọn si igbẹ́, ki emi ki o le jère Kristi" (Filippi 3:7, 8). Kiki nipasẹ Jesu nikan ni oun (tabi ẹnikẹni) le ri igbala.

Awọn eniyan wà lode oni ti wọn rò pe bi wọn ba lọ si ile-isin ni oorọ̀ Ọjọ Isinmi, ti wọn kò si ṣe ibi si ẹnikẹni, wọn o lọ si Ọrun. Awọn ẹlomiran rò pe bi awọn ba lọ si ile-isin ni Ọjọ Isinmi awọn Ju ti wọn kò si jẹ ẹran, wọn o lọ si Ọrun. Awọn ẹlomiran a maa duro ni ẹba opopo ọna lati ta iwe ni ero pe ni ṣiṣe bẹẹ awọn yoo ri ọna lati wọ̀ Ọrun. Bi eniyan tilẹ fi gbogbo ayé rẹ̀ fun iranlọwọ awọn alaisàn ati awọn alaini ninu iṣẹ itọju awọn alaisàn eyi kò le gba ọkàn rẹ̀ là.

**"Kilo le wẹṣẹ mi nu?...**

**Kilo tun le wo mi san?**

**Ko si lẹyin Ẹjẹ Jesu."**

Paulu ti pa gbogbo okiki rẹ̀ gẹgẹ bi Ju tì si apakan ki o ba le bá Jesu rìn ki o si gbọran si awọn ẹ̀kọ́ Rẹ̀. Ọna kanṣoṣo ni a le gbà lati ri igbalà: "A kò le ṣe alaitún nyin bi" (Johannu 3:7). Ohun atijọ gbọdọ kọja lọ -- a nilati pa irúgbin ẹ̀ṣẹ run – ki ohun gbogbo si di ọ̀tun ninu igbesi-ayé wa bi a ba fẹ wà ni imurasilẹ lati lọ si Ọrun.

Lẹyin gbogbo nnkan wọnni ti Paulu ti kọ̀ silẹ, o tun rò pe nnkan miiran kù fun oun lati ṣe sibẹ. O ṣe i ṣe sibẹ pe ki o padanu iye ainipẹkun bi kò ba rin pẹlu iṣọra. O n sa gbogbo ipa rẹ̀ tobẹ̀ẹ ti o le fi wi pe, "Emi nlepa lati de opin ire-ije nì fun ère ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:14).

### Awọn Ọmọ-Ibilẹ Ọrun

"Nitori ilu-ibilẹ wa mbẹ li ọrun," a le tun sọ eyi lọna miiran bayi pe, Ọmọ ibilẹ Ọrun li awa iṣe. Nigba ti a ba tun wa bi ti a si di ajumọ-jogun pẹlu Kristi, a jẹ́ ọmọ-ibilẹ Ọrun, a si nilati gbé igbesi-ayé wa ninu ayé yii gẹgẹ bi aṣoju "Ilu-ibilẹ" wa. Njẹ awọn eniyan ha le sọ pe Onigbagbọ́ ni iwọ i ṣe nipa igbesi-ayé ti o n gbé?

Nigba kan nigba ti Jesu rán awọn diẹ jade ninu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati lọ waasu, wọn pada pẹlu ayọ̀ nlanla nitori awọn ẹmi eṣu n tẹriba fun wọn. Jesu dahun: "Ẹ máṣe yọ̀ si eyi, pe, awọn ẹmi nforibalẹ fun nyin; ṣugbọn ẹ kuku yọ̀, pe, a kọwe orukọ nyin li ọrun" (Luku 10:20). Ki a kọwe orukọ wa ni Ọrun ni ohun ti o ṣe pataki julọ ni igbesi-ayé wa. Lẹyin ti a ba tun ti kọ orukọ wa sibẹ tán, a nilati ṣọra lati ri i pe a pa a mọ́ sibẹ. Bi a ba tún dẹṣẹ, lẹyin ti a ti gbà wá là, a o pa orukọ wa rẹ́ kuro ninu iwe Ọlọrun. O ni: "Ẹnikẹni ti o ṣẹ̀ mi, on li emi o parẹ́ kuro ninu iwé mi" (Ẹksodu 32:33). Nigba ti a ba kọ orukọ wa si Ọrun, a o maa ni inudidun lati maa sọrọ nipa nnkan ti Ọrun. "Nibiti iṣura nyin bá gbé wà, nibẹ̀ li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu"(Matteu 6:21).

### Ipadabọ̀ Oluwa

Ireti ologo ti Onigbagbọ́ ni ni lati lọ soke nigba Ipalarada Ijọ. O le ṣẹlẹ nigbakugba, nitori naa o ṣe pataki lati maa wà ni imurasilẹ nigbagbogbo. "Ẹ jẹ ki ipamọra nyin di mimọ̀ fun gbogbo enia." Jẹ ki awọn eniyan ri i pe iwọ n gbe igbesi-ayé rẹ fun Kristi, nitori Oluwa n bẹ nitosi. Maa lo akoko gbogbo bi ẹnipe Jesu le farahàn nisisiyii.

### Ẹni ti O n Ru Ẹru Wa

"Ẹ máṣe aniyàn ohunkohun." Ko gbogbo aniyàn rẹ lé Oluwa lọwọ ki o si jẹ ki O ba ọ yanju awọn iṣoro rẹ, nitori Oun n ṣe aniyan lori rẹ. Jẹ́ ki O pese fun aini rẹ má si ṣe kún fun aniyan nipa ohun ti iwọ le ṣe alaini ni ọjọ ọla. Jesu wi pe: "Ẹ máṣe ṣe aniyan nitori ẹmi nyin ohun ti ẹ ó jẹ, ati fun ara nyin ohun ti ẹ o fi bora. Ẹmi kò ha jù onjẹ lọ? tabi ara ni kò jù aṣọ lọ?" (Matteu 6:25). O ṣe ohun pataki lati ni igbala ninu ọkàn wa ju lati ni onjẹ ati aṣọ lọ. Igbala wa ni ìye wa. Ṣugbọn pẹlu eyini, Oluwa mọ ohun ti a ṣe alaini O si ti ṣe ileri lati pese rẹ̀ fun wa, bi a ba gbẹkẹle E. "Ẹ sá wò ẹiyẹ oju ọrun; nwọn ki ifunrugbin, bẹ̃ni nwọn ki ikore, nwọn ki isi ikójọ sinu abà, ṣugbọn Baba nyin ti mbẹ li ọrun mbọ́ wọn. Ẹnyin kò ha san jù wọn lọ?" (Matteu 6:26). Njẹ o ṣe akiyesi pe Jesu wi pe a "san jù" awọn ẹyẹ ti Oun n ṣe itọju rẹ̀ lọ?

### Bi a ti Igbadura

Paulu Apọsteli fun wa ni awọn àmọran rere nipa bi a ti igbadura. O ni: "Ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ, ẹ mã fi ibere nyin hàn fun Ọlọrun" (Filippi 4:6). Nigba ti o ba bẹrẹ si igbadura ranti diẹ ninu awọn nnkan ti Ọlọrun ti ṣe fun ọ. Gẹrẹ ti o ba ti bẹrẹ si idupẹ fun awọn nnkan wọnni ni ayọ̀ yoo kún ọkàn rẹ. Bi o ko ba le ronu ohun rere kan ti Ọlọrun ṣe fun ọ, rò nipa ile Ọrun ti O ti lọ pese silẹ fun ọ, ati pe iwọ yoo ni anfaani lati lọ wà pẹlu Jesu. Yọ̀ nitori Ọlọrun ti wi pe, "ẹnikẹni ti o ba fẹ" le wa. Gbogbo wa ni anfaani yii wà fun. Dupẹ lọwọ Ọlọrun fun oorùn daradara, fun awọn itanna ati igi ti o n mú oju-ilẹ lẹwà, fun ojo ti n bomirin eweko ti Ọlọrun dá. Ọpọlọpọ nnkan ni o wà ti a le maa dupẹ lọwọ Ọlọrun fún. Bi a ba ti n ni ẹmi imoore sí nipa ohun ti Ọlọrun fi fun wa, bẹ̃ni a o maa ni igbagbọ́ si i lati maa gba awọn ẹ̀bun ibukun Rẹ̀. A o bẹrẹ si ini ero yii ninu ọkàn wa pe Baba olufẹ tootọ ni Ọlọrun Ẹni ti n ṣọ ẹ̀ṣọ lori wa, ti O si n fẹ lati maa ṣe rere fun awọn ọmọ Rẹ̀.

**Itẹlọrun**

Paulu kò bikita nipa bi ohun ini ayé ti oun ni ti pọ̀ tó tabi ọlá ti awọn eniyan le bù fun un. O ni: "Ipòkipo ti mo ba wà, mo ti kọ́ lati ni itẹlọrùn ninu rẹ̀" (Filippi 4:11). Bi ó ba ni ọ̀pọ ó tẹ́ ẹ lọrun. Oun a maa dupẹ lọwọ Ọlọrun fun eyi. Oun ki igberaga nigba ti awọn eniyan ba n sọrọ rere nipa rẹ̀, tabi ki o maa ṣogo ninu ọpọ nnkan ti ó ní. Ṣugbọn bi ohun ti ó ni kò tilẹ to nnkan oun ki i kùn. "Diẹ pẹlu ibẹ̀ru Oluwa, o san jù iṣura pupọ ti on ti iyọnu ninu rẹ̀" (Owe 15:16). Nigba ti ohun gbogbo ba lọ tán, ti o fẹrẹ má si onjẹ fun un lati jẹ, oun le yọ̀ sibẹ. Ki i ṣe nitori oun tikara rẹ̀ ni o ti ni irú iwa bẹẹ tẹlẹ, ṣugbọn Ọlọrun ti ṣe iyipada ọkàn rẹ̀ ti o fi le wi pe: "Ẹ mã yọ̀ nigbagbogbo. Ẹ mã dupẹ ninu ohun gbogbo" (1 Tẹssalonika 5:16, 18). Oun kò wi pe ki ẹnikẹni ṣe ohun ti oun tikara rẹ̀ kò ṣe. O ti di "alabapin" ninu awọn ọ̀rọ ti o n waasu.

Idi rẹ̀ ti Paulu fi le waasu lọna iyanu bẹẹ, ti o fi le dá amọran ti n gbéniró bẹẹ fun ọ̀pọlọpọ ijọ, ti o si jẹ́ atilẹyin ati itunu fun awọn Onigbagbọ́ lati igba tirẹ̀ titi di akoko tiwa yii, ni pe o gbẹkẹle Ọlọrun patapata. O ni: "Emi le ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹniti nfi agbara fun mi" (Filippi 4:13).

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ilepa ti o leke lọkàn Paulu?

2 Sọ diẹ ninu idi rẹ̀ ti Paulu fi jẹ́ Onigbagbọ́ ti o layọ̀.

3 Awọn wo ni iran Abrahamu nipa ti ẹmi?

4 Ẹtọ́ wo ni Paulu ni si Ọrun, gẹgẹ bi ẹsin awọn Ju?

5 Bawo ni Paulu ti ka awọn ẹ̀tọ́ wọnyii si tó lẹyin ti o ri igbala?

6 Awọn wo ni ọmọ-ibilẹ Ọrun?

7 Ki ni yoo pa orukọ wa rẹ́ kuro ninu Iwe Ọlọrun lẹyin ti a kọ ọ́ sibẹ?

8 Ta ni n ṣe itọju awọn ẹyẹ? Bawo ni a ṣe le fi wa wé awọn ẹyẹ?

9 Bawo ni a ṣe nilati gbadura?

10 Ki ni Paulu Apọsteli sọ nipa itẹlọrun?